# IROHIN IMỌLẸ

*IMỌLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA*

NO 875 FRIDAY DECEMBER 18, 1964 (2D)


## SHOYINKA FILẸ ṢAṢỌBORA

EBUTE—MẸTTA:— Ariwo nla ta, okiki si kan kakiri gbogbo ilu Ebutte—Mẹtta yika ilẹ Naijiria ni kutu owurọ ana ọjọ ọjọ'Bọ ti ise ọjọ kẹtadinlogun, oṣu yi nigbati Ọgbẹni Jacob Fọlọrunshọ Shoyinka jalaisi ninu ile rẹ ni nomba 68, Cliford Street, Ebutte Mẹtta lẹhin ti o ti di ẹni ọdun mẹtaleladọta (53 Years) laiye.

Lẹṣẹkẹṣẹ ti Shoyinka ku, ni aburo rẹ, Ọgbẹni J. O. Shoyinka, abigege ku bi ojo, onitan Ajiran Ilu awọn Oku, ti gbogbo aiye mọ bi ẹni mọ owo ti tẹ waya si gbogbo awọn ẹbi ati ọrẹ ni Naijiria ati oke-Okun wipe "BABA SALAISI LANA, Ẹ MAA BỌ WALE O"

Ki Ilẹ to ṣu ni ana ni awọn enia na ti de si Eko, ti gbogbo wọn ṣe aisun titi ilẹ fi mọ kedere ni owurọ yi ninu ile Ologbe na ni nọmba 68, Cliford. Orisirisi ilu, ijo ati orin ẹyẹ ni awọn enia na fi nṣere lati alẹ ana di owurọ yi, Ọgbẹni J. O. Shoyinka ati ọmọloku, Abiọla Shoyinka na wabiwọsi owo.

Ni deede agogo mẹrin irolẹ oni ni nwọn o lọ gbe oku rẹ ni Ile Iwosan nla Eko, nibẹ ni nwọn o si ti gbe lo si itẹ-oku Ikoyi nibiti nwon yio tẹ ẹ si ti nwon o si ṣe isin ikẹhin fun un.

Ki Ọlorun da awon omo rẹ si.

# ẸGBẸ UPGA YIO PẸṢE IṢẸ FUN GBOGBO ENIA

**IBADAN:— Ọgbẹni Bọla Ige, akọwe ipolowo ati Ikede ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ ni Ibadan ni alẹ ana ọjọ ọjọ 'Bo ti ise ojo kẹtadinlogun oṣu yi wipe ẹgbẹ UPGA yio pese iṣẹ fun gbogbo awọn ti ko ri iṣẹ ṣe bi awon enia ba le dibo wole fun ẹgbẹ na ti Apapo Ijoba ba si le wa lowo won.**

Ọgbẹni Bọla Ige pe akiyesi gbogbo enia si asiko yi, lati fi we asiko ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ wa lori aga akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, ki nwọn o si wo asiko isisiyi, eyiti o ba dara ninu mejeji.

Ọgbẹni Ige tun fi ye gbogbo enia wipe, gbogbo awọn onisẹ ọba, akọwe Olukọ ati awọn Onisowo ni nwọn ni owo lọwọ, ti nwọn ri jẹ ti owo si tun ṣẹku ninu apo wọn pẹlu idẹra ni nwọn si ngbe, ni asiko Ijọba Awolọwọ.

O tun pe akiyes awọn enia si iru aye ti Ijọba Dẹmọ Ipinlẹ Iwọ Orun fi gbogbo awọn enia si loni

O ni ti a ko ba nisọ asọdun ti a ko si ni fi ọmọri igba kan bọ ọkan ninu "Ẹgbẹ Dẹmọ ti ba gbogbo iṣẹ rere ti Oloye Awolọwọ ṣe si Ipinlẹ Iwọ Orun jẹ, to bẹ ti ko fi si ẹniti o tun wa ninu idẹra ati ifọkanbalẹ ni Ipinlẹ mọ loni"

Gbogbo awọn ọmọ wa ti Ọlọrun fun ni ẹbun ẹkọ mimọ ti nwọn ni iṣẹ lọwọ



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**

Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

ti nwọn si wa ni ipo atata ni Ipinlẹ na nigbakan ri, ni nwọn ti sa kuro nisisiyi ti nwọn wa iṣẹ lọ si Ipinlẹ miran.

"Awọn Oṣiṣẹ ni Ijọba Dẹmọ ndalagara ti nwọn si nyọ wọn lẹnu ni ojujumọ ti nwọn si nfi ipa mu wọn ṣe ohun ti nwọn ko fẹ lati ṣe.

"Eyiti o tilẹ wa burujulọ ninu ọrọ na ni wipe, gbogbo awọn Oṣiṣẹ Ọba ni Ipinlẹ yi loni ni Ijọba ko san owo oṣu fun deede tabi ni asiko.

Ohun ti Ijọba si tun bẹrẹ si ṣe nisisiyi ni lati maa da gbogbo awọn oṣiṣẹ ti nwọn ba ṣe akiyesi rẹ pe nwọn ki iṣẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ duro lẹnu iṣẹ onjẹ ojọ wọn.

Ọrọ awọn olukọ ni gbogbo ile-iwe lo wa burujulọ loni ni ipinlẹ yi.

Ijọba Dẹmọ ti bẹrẹ lati ma fi iya jẹ awọn olukọ ti ko ba ṣe Ijọba wọn, nwọn si nda wọn duro lẹnu iṣẹ.

Bi nwọn ba wipe awọn olukọ ile-iwe kan ko ṣe ti awọn, nwọn a da gbogbo awọn olukọ ile iwe na duro, nwọn a si ko awọn ọmọ wọn lọ si ile-iwe miran.

" Nwọn a sọ fun awọn Olukọ na pe ko si ise mo. Ni agbegbe ti Ile iwe mẹta wa, nwọn a siko gbogbo awọn ọmọ ile we ibẹ jọ si oju kanṣoṣo.

" Awọn Olukọ ti o ba nse ẹgbẹ Dẹmọ ni nwọn o gba si ile iwe, nwọn a si da awọn ti ko ṣe ti wọn duro."

" IYIPA RERE ".

Ọgbẹni Bọla Ige wa kesi gbogbo awọn enia Ipinlẹ yi lati kọ ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ninu ibo ti mbọ yi ki nwọn o si dibo fun ẹgbẹ UPGA ẹgbẹ oṣelu kanṣoṣo na ti o sọ wipe o le gba awọn enia Ipinlẹ yi silẹ ninu aikori isẹ ṣe eyiti ẹgbẹ Dẹmọ ko wọ ilu

Bi ẹ ba mọ wipe ẹ ko fara mọ ẹgbẹ Dẹmọ ti ẹsi nfẹ alafia ati idera eyiti gbogbo yin mọ ti ẹsi le jẹri si ninu ọrọ mi yi, wipe ẹgbẹ Afenifẹre le ṣe fun nyin, ani eyiti o ti ẹgbẹ na ti ṣe ri, ẹdido fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu ibo yi.

Ẹnyin olukọ, onisẹ ọba ati gbogbo ẹnyin onisowo ati ẹnyin agbẹ, gbogbo yin ni ẹmọ onisọwo anfani ọkọọkọjọkan eyiti ẹni ni asiko Ijọba oloye Ọbafẹmi Awolọwọ.

Anfani nla lo wa fun yin

Wo Oju Ewe Kẹfa

## Ijoba Ragabu Tarka

**TIV:- Gbogbo enia lo yanu silẹ ti nwon fẹrẹ mafẹ pade mọ nigati nwon gbo lati inu ero aṣoromagbesi lana ojo ojo'Bo ti iṣe ojo ketadinlogun oṣu yi, pe awon olopa mu Ọgbeni J S Tarka.**

Agbo wipe bi o ti fe pada ninu ile re lehinti o ti lo gba iwe awon adibo ni awon olopa ba mu u. Bi a ba ti gbo oro na si ẹ o tun ma a gbọ

## IPADE UPGA

Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA yio ṣe ipade loni ni deede agogo marun irọlẹ ni opopo Amutọ.

Awọn ti o wa ni Ebute- Mẹtta yio ṣe ipade ti wọn ni Ipọrin ni agogo marun kanna

Nwọn npe gbogbo ọmọ ẹgbẹ lọkunrin ati l'obinrin.

Tete ra Irohin Imọlẹ tirẹ lọla ki o bale mọ ibi ti wọn ma ti ṣe ipade ti ọla.

IKEDE:—

# ISIPAYA KINI

## Ọtẹ Ti Awọn Ti Ki iṣe Ọmọ Yoruba Di Mọ Oloye Benson Lati Le Gbe Ajeji Si Ita Fun Ibo Didi



**Oloye T. O. S. Benson**

Lati Ọdọ Awon ti ki iṣe Yoruba ọmọ ẹgbẹ N C N C Ti nwon ngbe Ilu Eko
C/o Oloye F. G, Onyinke,
76, Abeokuta Street
Ebute – Mẹtta
Ọjọ kẹwa oṣu August 1964
Si
Apapo Igbimọ Amuṣẹṣe, ti nwọn nṣe ipade ni Umuahia, ki o de ọdọ wọn lati owo Akọwe Apapọ Olu Ile iṣẹ N. C. N. C.

EKO

Ẹnyin ara ilu wa,

TI NṢE ETO LATI YAN AWỌN AṢOJU FUN IBO APAPỌ ỌDUN 1964 NI EKO

Awa ti orukọ wa wa ni isalẹ iwe yi, ti a ki iṣe ọmọ Yoruba ninu ẹgbẹ NCNC l'Eko lẹhin aṣaro lori bi gbogbo nkan ti nlọsi ni asiko yi, a fi iwe ẹbẹ yi ranṣẹ si ijoko ẹnyin ada pọ Igbimọ Amuṣẹṣe ti nṣe ipade ni Umuahia fun igbayẹwo.

1 Bi a b f i oju inu wo a o ri wipe aye ọtọ ni ilu Eko wa ninu ofin iṣelu wa, gẹgẹbi aye ijoko fun apapọ Ijọba, awa gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ ti ki iṣe Yoruba, wa ni aye kan nibiti, a ba wo awọn ohunti o ti nṣẹlẹ lati ẹhin wa, a ri daju pe ẹgbẹ NCNC lo ni aṣoju ti nṣe ifẹ wa ninu ile Igbimọ aṣofin apapọ Ijọba orilẹede yi.

2· Lẹhin igbati o si ti jẹ wipe gbogbo wa ni a nṣe olotitọ si ẹgbẹ tabi ọmọ ẹgbẹ ti ko ṣiyemeji, ti si nlakaka ni gbogbo igba fun ilọsiwaju ninu ibo si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ tabi ile Igbimọ apapọ Ijọba a le ro pe o tọ, o si yẹ lati kesi ẹnyin aṣiwaju ẹgbẹ wa lati fun wa ni anfani lati fi ero ọkan wa k n lo ti eto yiyan aṣoju sode fun ibo apapọ ti mbọ yi.

3. O ṣe pataki lati tun mu ẹnu kan an, nihin pe, lẹhin ajọro o h u n idena ti ẹgbẹ NCNC fi nkuna ati lati mu oke ninu ibo larin ilu Eko larin ọdun mẹ a sẹhin a o ri daju pe i k u n a ẹgbẹ wa ni ilu E k o laipẹ yi, ti ẹgbẹ na ko fi moke ni aini itẹlọrun larin awọn ọmọ ẹgbẹ wa, ti ki iṣe ọmọ yoruba eyiti o ngmu awọn ọmọ ẹgbẹ na da aguola ti nwọn si nkọ eti ikun si ẹbẹ ẹgbẹ N. C. N. C. ni awọn asiko ibo koda ni igba miran ti ọmọ ẹgbẹ na ma nju iwe ibo wọn sinu apoti awọn ẹgbẹ Alatako.

4. Bi a ba wo a w ọ n akọsilẹ rere, ẹgbẹ (N. C. – N C.) ni Eko a o ri daju pe, ni Yaba, S u r u l e re, Apapa ati agbegbe Ikoyi nibiti ko si awọn Yoruba ni ẹgbẹ N. C. N. C ti ma a nmoke nigbogbo igba. Sugbọn nitori ajeji, ọpọlọpọ ninu wọn ko ni ifẹ ninu bi ẹgbẹ ti ṣe nlọ ni ojojumọ, nwọn kii tilẹ wa si Ile iṣẹ, de ibiti nwọn o yọ wipe nwọn o ti yan wọn si ipo kan ni asiko Ibo. Nitori idi eyi, awọn ọ m ọ Yoruba ti nwọn nwa si pade deede, ti nwọn si pọjulọ ninu I g b i m ọ, ni nwọn ngni anfani lati yan ni aṣoju ẹgbẹ si gbogbo aye ijoko l'Eko, s i bẹ na awọn kan ninu wọn ko faramọ ẹgbẹ N. C.N. C. ni asiko ibo, gẹgẹbi o ti ṣe han si gbogbo enia, pe, ẹgbẹ wa ki imoke ninu Ibo Apapọ ni agbegbe ti awọn ọmọ Yoruba pọsi. F u n apẹrẹ agbegbe "F" Ward aye ijoko mẹfa Ward aye ijoko mẹfa 'A' Ward a y e ijoko mẹrin ati 'B'' Ward aye ijoko mẹfa.

5. Nitori awọn idi wọnyi awa paapa mọ lara wipe asiko ti wa de nisisiyi, lati fun wa ni anfani lati ma a ka eso iṣẹ wa nibiti a gbin si atipe a si nkesi ijoko Igbimọ Amuṣẹṣe ẹgbẹ N.C.N.C. lati ri daju pe, nwọn fi aye ijoko kan fun ẹnikan ti ki iṣe ọmọ yoruba ninu aye ijoko mẹrin ti o wa Eko. Awa gbagbọ wipe, bi ijoko Igbimọ Amuṣẹṣe ba le ṣe bayi, awa ti di iṣe ọmọ yoruba yio le ni igbẹkẹle ninu igbimọ na ni ayọ ọrọ yi si le jẹ ti awon ni ikẹhin.

6 O tun ṣe pataki fun wa lati tun sọ fun ijoko nyin pe ẹbẹ yi ṣe pataki nitoripe awọn kan ninu nwọn ti beresi ya ẹya kan sọtọ, nwọn si nsọ labẹlẹ kakiri nwọn tilẹ npero ọrọ sl, ọkan awọn ọmọ yoruba wipe. nwọn ko gbọdọ dibo fun ẹniti ki iba iṣe ọmọ yoruba, ohun ti awọn enia na si gbẹkẹle ti nwọn si tun nsọ kakiri ni wipe awọn ọmọ yoruba lo pọju ninu Igbimọ Amuṣẹṣe ẹgbẹ NCNC ki awọn enia na si lo aye wọn lati yan ọmọ yoruba bi o tilẹ jẹ wipe, ibiti awọn ọmọ yoruba ko pọ si ni agbegbe Eko.

7. A lero wipe ninu gbogbo ohun ti a ti sọ silẹ nitori iṣọkan wọnyi i j o k o Igbimọ nyin yio gba imọran wa yi yẹwo ṣugbọn ti o ba jẹ wipe, ọna yi lodi si eto ofin ẹgbẹ wa, ti ẹ ko ba si ri ọna lati g b e ọrọ yi gba, ko si ohunti a tun nfẹ ki ẹ ṣe ninu ipade nyin yi ju awọn nkan wọn yi lọ.

Pe Igbimọ ti yio yan awọn Aṣoju ti a o dibo fun na ni lati wa lati adugbo ti a o ti dibo. Eyi ni a lero wipe, yio ṣe iranlọwọ fun wa ti ko fi ni jẹ wipe, ẹnikan yio fi fi ipa tabi agbara yan ẹniti a ko fẹ fun wa.

8. A lero pe iwe ẹbẹ ti a kọ si nyin yio jẹ itẹwọgba loju nyin, ẹ ko si ni kọ imọran wa na silẹ.

A duro bayi, Ẹnyin ara ilu wa. Fun ati ni Orukọ awa ti a ki iṣe Yoruba ti a ngbe ilu Eko.

1. F. G. ONYIUKE
2. F. M. MORONU
3. E. U. UNIGWE
4. J. O. AMUGO
5. F. U. ANYIAM
6. L. S. SOLOMON
7. G, N. EZIMORAH
8. A. O. OSUALA
9. H. ESSIEN
10. J. O. IRAGHONGE

# IWE SI OLOTU

## Ẹ Maşe Fi Aye Gba Awon Ole

Dakun, Olotu Iwe Irohin Imọlẹ gba mi laye niwọn ibaranpẹ ninu iwe Irohin rẹ lati kesi gbogb o awọn onkawe wa gbogbo ati paapa julọ awọn ọmọ Ilu wa – Mushin wipe kt nwọn o mase fi aye gba awọn Ole.

Lẹnulọlọ yi ni a gbọ wipe awọn Ọlọsa kan lo gba owo osu awon oşişẹ Ile işẹ ọkọofurufu lowo oga won ti o lo gba owo na ni Ile ifi owo pamosi [Bank) ti nwon si ji owo na gbe lo.

Ni tooto oro na wa ni owo awon Ọlopa nisisiyi, şugbon o yẹ ki a le ma kilo fun ara wa.

Ẹ jowo bi odun ti mbo yi awon ole folefole Ọlosa kun arin ilu ti nwon nrin gbaşegbaşe regbedẹ kakiri ilu.

Bi ẹ ba mu owo lowo lo si ode ẹ mase fi owo nyin jafara ẹ ma si se gbagbe lati ti ferese ati Ilẹkun ile nyin ti ẹ ba nlo si ode tabi nigbati ẹ ba fẹ sun ni alẹ.

Ki Ọlorun maşe ẹru wa ni ẹru awọn Ọlọsa o. Ki oju ma ri ib ẹşẹ ni Ogun.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ Ọba koni sa nyin lẹşẹ O.

Emi ni
Aina Aiyelagbe
MUSHIN

## Kabo, Ejongboro

Olotu Jọwọ gba mi ni ayẹ ranpẹ ninu gbajumọ iwe Irohin-Imọlẹ rẹ lati fi ki Ọgbẹni wa, abi gege kubi ojo ti orukọ adape rẹ a ma jẹ Ejongboro ku a bọ irinajo si ilu okere ti o ti şe lọ lati nkan bi oşu mẹfa sẹhin.

In u wa dun pupọ nigbati a ri ka ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ Aje ti işe ọjọ kẹrinla oşu yi nipa Irohin aladun ti Ọgbẹni wa na kọ nitori lati nkan bi oş n ẹfa sẹhin ni a ko ti gburo Ejongboro ti a si nbere rẹ ni ojoojumọ.

Lakotan ọrẹ mi mo ki Ejongboro kabọ, a si lero pe yio fun wa ni awọn irohin aladun ti o mu bọ ninu irinajo rẹ.

Emi ni,
FalilatuArẹaga
EKO.

## Aiyekoto Ma Şe Bẹru

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Irouin-Imọlẹ to nta bi akara gbigbona lati kesi ọlọla wa Bisi Ọnabanjọ eyi ti a da ipe rẹ njẹ "Aiye kotọ" ninu Iwe irohin pe ki o mu lẹhin rara ati pẹ awa ọmọ Ijba mbẹ lehin rẹ gboin-gboin lọjọkọjọ.

Mo si tun kan saara si iri ajo ipolowo ibo rẹ ti o şe si awọn ilu kan laipẹ yi ni agbegbe Ijẹbu cyi ti ninu awọn ilu si jẹ Isiwọ, Oke Ako ati odolẹwu awa ko şe pe ki a ri pe ẹgbẹ Afẹnifẹre wọle ki nwọn si şe nkan ti a nfẹ fun wa lẹhin ti nwọn ba ti gba Ijọba tan.

Ijọba ti Oloye Ọbafẹmi şe Olotu rẹ ni ipinlẹ Iwọ Orun si tu wa lara a si ri anfani rẹ sugbọn lati igbati awọn enia ti ko fẹ ire mọ e .k ji wọn de bẹ ni gbogbo nkan yatọ nitori aji awa si wa lẹhin ọgbẹni Aiyekotọ ki o maşe bẹru nitori pe idaniloju ti wa pe yio bori ibo to mbọ yi Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹgba mi.

Emi ni
P. O. Ọshinukan
EKO

## Ejongboro Tajo De

O l o t u Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye ninu i w e nyin oloyin mọmọ, a l a k a gbadun ti orukọ rẹ nje Irohin Imọlẹ lati fi ki Ọgbẹni wa Ejongboro ti orugbẹ rẹ ti gbẹ awa onkawe Irohin Imọlẹ lati nkan bi oşu melo s'ẹhin ku abọ.

Nigbati mo ri ka mo ri Ọgbẹni wa na ti de ni r inn ti bẹrẹ yo sẹşẹ pẹlu o o de bayi o de ! ẹniti a nwtin wọ-Ejongboro de, Ọkunrni a wa nku wọkoko de. Enia ti wa onkawe Irohin Imọlẹ.

kori bi akara ti debẹni wa Inu mi dun pe Ọg nipa işẹ na tun lọ ẹkọ ijnlẹ siyioni a si ni on lero pe ni Ejongbo tun ma gbadun lọ.

ro ju ti atẹhin w aangfẹ gbọ iniNitori idi e yijo nibor o ulpa irinajo jnlọinlẹbiti c ni ie ẹkọ giga julọ ni işẹ rẹti ni un lọ kọ ẹkọ

Emi ni
Dele Ogunlẹyẹ
SHOMOLU

## Ẹ Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Fun Irohin Aladun Ati Eto Ipolowo Ibo


# KẸRẸ O!

Kurani Ọgbọn Eşu ti a şe Larubawa ati itumọ ri sinu Yoruba 25/- Postage 1/6d, Iwe Adura pataki d e Ar is ki ati işẹgun lori ( hun gbogbo lati ilẹ M a 1/6 Iwe Atumọ Ala ati Adura Ala ibajẹ ti a ti nta ni 4/- o ti din si 2/6d Afọmọ isin Mohammed 1/— lọdọ:—

Tete ra tirẹ
Ẹ SAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
(Leti Ọja Jankara l' Eko

# Kini F. Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen ) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati orişirişi asọ ti o ba n fun fifọ ati lilọ ni i eju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ
JOYCELAUNDRETTESERVICE
34, Ojo — Oniyun Street,
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A .e wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranşẹ si wa.

Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi işẹ wa ti dara to owo pọọku ni a si ngba

# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



CYCLOVEN

Aworan ẹgbọ yi fihan gba gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wa ni ara rẹ ti nyọọ lẹnu nigba gbogbo. Ibẹ ni a n p e ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba şe igbọnşẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si soro pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni o wa ti ti nta kakiri ode nisisiyi ana nwọn ma a npolowo nwu un iwosan rẹ şugbọn boyi fa le i ri mẹwa ninu awọn gun ti o leşe iwosan arun iy daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn gbe lọ si Ile iwosan lati lọ ge eyiti o ba nyọ jade omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patpaata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwu ẹran Şuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ sode ninu omuşu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani şẹşẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ti le tangiboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICINE STORS
4 Tinubu Square Lagos
WATER-LOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22678 Nigeria, (Ọja Ita faji
ATI NI ŞỌBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN.

# Eyi To IronuFun Ẹyin Ọmo Igbomina

LATI ỌWỌ HAMED ODẸ TUNDUN

Ẹ ku deede woyi ẹnyin enir mi ni ilẹ Igbomina, Ọffa ni Ekiti mo ro pe akoko na ti nto bayi lori gẹgẹbi a o a mu ero ọkan wa sọ ati bi a ṣe le jagun molu lori okan ta wa nibẹ bayi, ali pe ọrọ mi yi si wa fun ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti lori eto idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi ati lati ronu si ẹgbẹ oselu ti ko fẹ ire ati ilọsiwaju mọ awọn ọmo ilẹ Igbomiua Ọffa, ati Ekiti eyi ti ise ẹgbẹ Olomi NPC

Pataki chun ti o mu ni ọ rọ mi yi ni wipe awọn ẹgbẹ NPC nsọ wipe ti awọn ba gba Ijọba awọn yio da iya jẹ ilu ti ko ba se ẹgbẹ NPC lori ohun ti nwọn sọ yi njẹ o ye ki o dibo fun ẹgbẹ NPC bi? Nitori pe awọn ti ko ti gba Ijọba ti won ti nyara se ohun ti awọn yio ṣe yi njẹ ti nwọn ba ti ri ẹni ti ko ba ṣe ẹgbẹ wọn pipa ko ni wọn yio pa? Mo fi eyi si eti gbọ gbogbo ọmọ igbomina Ọffa, ati Ekiti lati ronu wọn jinlẹ ki nwọn to dibo fun ẹgbẹ NPC Emi ko gba nyin ni imọran lati dibo fun ẹgbẹ NPC rara, ni ori ohun ti nwọn yio ṣe fun awa Igbomina Ọffa, ati Ekiti ni nwọn sọ fun wa yi

Siwaju si Ẹgbẹ ti o nfẹ ilọsiwaju awa Igbomina ni ẹgbẹ Afẹnifẹre Nitori na mo bẹ gbogbo ọmọ ilẹ Igbomina lati dibo fun Afẹnifẹre nitori ẹgbẹ a ni o nfẹ alafia fun awa Igbomina Ọffa ati Ekiti Ọlọrun Olodumare yio si jẹ ki Ẹgbẹ Afẹnifẹre wọle ni ilẹ Igbomina ani ẹsẹ Mo si tun rọ gbogbo ọmọ Igbomina Ọffa ati Ekiti lati lọ sile lati lọ dibo fun awọn Aṣoju wa, awọn bi Ọlawọyin Dada ati Hassan Balogun Ọlọrun Olodumare yio ba wa ṣẹgun awọn ẹgbẹ Olomi amin aṣẹ.

Lẹhin na awọn ẹgbẹ N. P. C. yio ma halẹ mọ nyin wipe ti ẹ ba lo si ile laijẹ pe ẹgbẹ N P C ni ẹ nse ki ẹ maṣe gba wọn gbo rara irọ ni nwọn npa ki ẹ ma ba dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ri Ẹ lọ ile lati lọ dibo fun Afẹnifẹre Ofin ko mu enikankan pe ko ṣe dibo fun ẹgbẹ kankan ohun ti o ba wu eni ni iṣe ẹgbẹ Oṣelu ti o ba wu enia ni iṣe

Nitorina ki ẹ ma ṣe ju ire ilẹ Igbomina Ọffa ati Ekiti nu Nitori pe nwọn ko ni ifan ri p Ẹru awọn Hausa ni Igbomina Ọffa ati Ekiti iṣe Ọlọrun Olodumare yio gbe wa le le ni ilẹ Igbomina amin aṣẹ Ẹ dibo fun ẹgbẹ UPGA

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Orire ọlọpọpọslio yd e is ọ, sọra kio mase fi ara rẹ wewu aisan, iwọ yio gbọọ irohin ayọ loni pelu.

PISCES (Feb 21 – Mar 20) Itẹlorun yio wa fun ọ ni ọna gbogbo, jẹki ohun gbogbo ti oba nse mọ ni wọntunwọnsi, mase ba ẹnikan ja rara.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ire ni ọjọ oni fun ọ ohun idunu kan yio de siọ ni asiri, ire yio pọ fun ọ ni owurọ.

TAURUS (April 21 - May 20) Ṣe ipinnu ere kan ti o le pani lerin, iwọ yio si ri ire pupọ nibẹ.

GEMINI May 21 – June 21) Ayi pada ire yio yi kan ọ, ọgbọn ori rẹ yio si gbe ọ ga, iwọ o si gba alejo tabi ki iwọ lọ se abẹwo enia ni ale oni.

CANCER (June 22 - July 22) Ohun kan yio selẹ ni owurọ ti yio kọọ ni ọgbọn mase kọ imọran ti wọn ba fun ọ silẹ ki oma ba gbe ara re sinu idanwo.

LEO (July 23 - Aug 23) Ohun gbogbo ti oba nse loni, yio ba ire pade mase lo akoko danu lori ọrọ ti koto ọrọ; ki oma ba di ire tirẹ lọwọ.

VIRGO (Aug 24 - Sept 23) Akoko ni lati de funọ ki oba le ri aye tun ọna rẹ se, ọwọ rẹ yio tẹ ohun ti o nfẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Fi eti silẹ ki gbọ irohin ti oba gbọ li owurọ yi mase sori kuukun, bi bẹkọ janba yio de siọ, iwọ yio si lagbara lati pasẹ lori ẹlomiran.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Sọra pupọ ki o ma ba gbe ara rẹ sinu idanwo owo oina, ki oma ba duuọ gbẹhin

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ri daju wipe oni alatilẹhin pupọ fun oh un kan ti ongbero lati se, fi ori tii ki oma si se fi agbara mu enia se kan, iwọ yio ni owo, n tori owo mbọ

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Sọra ki mase da si ara rẹ lọrun nitori gbogbo ara rẹ tidi hungẹ-hungẹ, bi bẹ kọ, iwọ yio ba ara rẹ ni biti ẹsẹ rẹ ko to ilẹ.


# ADURA JẸ J'OGUN LỌ

Iwe Adura pataki fun Arisiki lati ilẹ Mesira 2/6
Iwe Adura Akanṣe ati apẹrẹ ile aiye.......... 2/
Afọmọ - isin Ojiṣẹnla Muhammed.......... 1/
Iwe Itumọ al ati Adura Ala Ibanujẹ.......... 3/6
Iwe Aniyan Irun ojojumọ ati Aniyan pataki fu Musulumi 1

Tete fi Owo ranṣẹ si:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Naijiria
(Leti Ọja Jankara l'Eko)

EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

# TESSYDRE

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti mẹji irufẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala losan tabi sun awọn iya wọn gbogbo Ogọrun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ sugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessyd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agọnyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyonu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osinu fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ ṣiṣu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro aftẹfẹ ati orisirisi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu ni ba Ehin HIHU" gbogbo. Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati san ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba ṣe am rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọsẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaye wọn ti wọn jẹun dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:—
WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

# Tani Oye Ọba Yẹ Ninu Awọn Enia Nwọnyi ?

## Lati Ọwọ Ẹṣọ

Eko:- Latl igba ti Ọba Adele keji ti w'aja ni ede koyede ti bẹ silẹ larln awọn ọmọ Ọba ati awọn Afọbaje lori wipe idile wo li o tun tosi ki nwọn fi jẹ oye Ọba Eko dipo Ologbe Adele keji ti o w'aja, awọn ọmọba ko iti fi ipinnu sori ẹnikan.



## Ologbe Ọba Adeniji Adele Keji

Ngbati Ọba Adele jẹ oye Ọba ninu Iga Idunganran nigbana ni Oluyẹ Ọmọ Dosumu ba du oye na titi ki o to bọ si Adele lọwọ lẹhin ti Oluyẹ si ku, ni Adeyinka Oyekaa tun bọ siwaju wipe, bi adele yio ba jọba, ki o lọ si iga baba rẹ. nitoripe Iga Idugaaran jẹ ti Dosunmu Baba on. Asẹhinwa asẹhinbọ Adele gbe Adeyinka la molẹ. Adeyinka sọ wipe iba ṣe wipe on ri ida mẹrin atiiẹhin ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe fun Adele keji nigbati on pẹlu rẹ nfa kokowa o daju wipe, gbangba pe ni yio aye Ọba Eko.

Diẹ ninu ijoye Eko ati awọn gbajumọ ilu Eko wo ro o wipe, ti otẹ yi, Adeyinka ọmọ oyekan ni o ye Ọba na tọ si. nitori pe o ti nawo nawo titi, o si guu li si ebute ofo. Oloye Saba ati Kọsọkọ sọ wipe awọn ko fi ara mọ Ọ b a Eru, Ọna ti nwọn ngba ti nwọn fi nyan ọba E k o nigba iwa rẹ. ni awọn fi ara mọ.

Awọn enia mẹfa ni a gbọ wipe nwọn fẹ da ifa le lori nisiyi (1) ni Buraimọ Modilẹ Idile Akinmọrin ni (2) Odunewu, Idile Oṣilokun ni (3) Taju Deen Idile Olusi ni (Ki iṣe Taju ọmọ Thomsou ni a wi o )

4. Adeyinka Oyekan, Idile Akintoye ni,
5. Ladele Ajọṣe idile Ologun - Kutere ati Bọlaji Adele, Idile Ado Eniti a gbọ wipe yio difa yan ọba na ni Oloye Fagbemi Ajenaku ti iṣe Araba Eko

on ni Oleye Ọjọn, ati Obanikoro yio ranṣẹ lọ pe, nitori pe on li ẹniti o difa yan Ọba Adele nigbati o mbẹ ni ọmọ Ọba ninu Iga Eletu Odibo awọn ijoye ilu ti a gbọ wipe nwọn o jẹri si ohun ti Ifa wi lojọ Jimọ ti o mbọ

ni Oloye Ọjọn, Eletu odibo, Eletu Iwaṣẹ, Obanikoro, Saba, Kosọkọ, Aṣọgbọn, Nwọn o bẹrẹ ifa na ni dida ni agogo mẹsan owurọ gẹrẹ ti Araba ba ti de.


## Gbanjo ! Gbanjo ! !
FUN ỌDUN KERESIMESI

A ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra tirẹ ki o to kasẹ nilẹ

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọọsi Mushin, sọka'ẹ ni Atẹ̀v.ọlara Bus Stop Bere ladipọ Street, ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRẸ. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile iṣẹ wa dojukọti ODUS SURF"

AWỌN ỌJA WA

Olubori Egbogl Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin tite ati etu ṣiṣe 20s di 17 Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Turari Isẹgun Ajẹ 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lẹsin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book dl 1s 6d
Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Forms
Certificate of Apprenticeship (mẹta] 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ṢẸṢẸ RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idaloju (oriṣiriṣi awọn fun Turari.
abẹla mimọ fun itaja (Kowo wọle pẹlu Turari 20/-
„ „ „ Isẹgun Ajẹ pẹlu Turari 20/-
Lọfinda tabi Ororo ipara fun itaja, Isẹgun Ajẹ ati arisiki 30/- Igo kan
Fi owo ranṣẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—
J. O. Shoyinka
5.Alaba Street
MUSHIN.



## Ogun Belubelu Tabi Lẹrẹ
ỌNA ỌFUN — ỌNA ỌRUN

Ewu nlanla ni lati fi abẹ si ọfun lati ge Belubelu o ti ṣe iku pa ọpọlọpọ enia nipa bayi ati 'an Ogun Ajẹbidan ti ati fi wo Ọgọnlọgọ enia san ni ọjọkan na. Ko Si Tun Ṣe Oluwarẹ Mọ Lailai.

Ẹ BERE LỌDỌ

Ọgbẹni Aro - Lambo
43, Koseh Street, Lagos.

A DAYS REMEDY FOR THE CURE OF
TONSILITIES
WITHOUT OPERATION
Price 12s 6d

